# ỌRỌ AKIYESI

1 Emi dupẹ lọwọ Ọlọrun Olodumare Ẹlẹda Adulawọ, ati gbogbo aiye fun ipamọ, ibukun, abo, ati iranlọwọ Rẹ lori mi ati gbogbo Ijọ wa, eyiti o fi ọkan mi balẹ lati ṣe atunṣe Iwe Adura mimọ yi, larin ọpọlọpọ atako lati ọwọ ẹnyin ọmọ Iya wa ninu awọ dudu yi, sibẹ na, Ijọ Ọrunmila Adulawọ nfi han yin pe eyi jẹ isin ajogun ba yin, ti orilẹ ede kan kole ba yin du rara, nitori a mu isin na jade larin ede, aṣa, ti ilẹ yin a si tun fi Woli ti yin han yin, eyiti o tọ ti o si yẹ ki ẹ ma ṣogo ninu rẹ, gẹgẹ bi orilẹ ede miran ti nṣe fun igbeleke ogo ilẹ wọn, yio dara pupọ ti ẹ ba le ran Ijọ yi lọwọ, ki ẹnyin ati awọn Iran ti o mbọ ba le ni ayọ pipe lori ilẹ ede wọn.

2 Mo dupẹ lọwọ awọn ọmọ Awo mi, ati awọn Akọrin fun iranlọwọ wọn lori gbogbo iṣẹ ti o wa ninu Ijọ, mo si dupẹ lọwọ awọn Igbimọ Ijọ, fun iṣẹ nlanla ti wọn nṣe fun ilọsiwaju Ijọ yi, nigbagbogbo. Mo si dupẹ lọwọ awọn Aṣipa pẹlu, fun suru wọn larin onirunru ati oniwai-wai enia, mo si dupẹ lọwọ awọn Ẹgbẹ ti o nṣe dei dei ninu Ijọ, fun apọn, wahala, ati ero pipe wọn, fun idagba soke Ijọ na ire ni gbogbo wa yio ri kari kari. Aṣẹ.

3 A ko fẹ ki ẹnikẹni ṣe ẹda iwe yi laigba aṣẹ Igbimọ Ijọ yi.

Emi ni tiyin ninu Odumare, ati ninu ifẹ ti Ọrunmila, ati Ẹla Awoye mimọ,

A. O. ỌṢIGA
Oluwo Ijọ.

Ọjọ Kini Oṣu Ope,
(1st. December 1942)